# IROHIN IMOLE

IMOLE OJO AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 729 FRIDAY, JUNE 26, 1964


## Ẹniti Iyawo Kọsilẹ Gun Ararẹ L'ọbẹ !

MUSHIN:-Ọrọ di bo duro o gbe, nigbati ọkunrin kan, Sule Abisoye ẹni ọdun mẹrindinlaadọta bọ si arin ode ninu ile rẹ ti o si mu ọbẹ olojumeji ti o fi gun ara rẹ ni isalẹ iku ni ọjọ Ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn ara adugbo na ti sare ranṣẹ si awọn ọlọpa lati wa wo engmọ ohun ara ti nwọn ri ni adugbo awọn lẹsẹkanna ni awọn ọlọpa sare de, ti nwon si sare gbe okunrin na lo si ile iwosan Ikẹja fun itoju ṣugbon okunrin na ku loju ọna ki nwo to gbe de ile iwosan.

Ẹniti nwon jijo ngbe inu ile kan na pẹlu okunrin na se alaye fun oniwe irohin wa pe isẹ akọwe isiro owo ni okunrin na nse ni Adapa Nigbati odi ose to koja yi ni iyawo okunrin na sa kuro lodo rẹ pẹlu awon omo rẹ meji nwon si wa si iyawo na pẹlu omo nwon ko ri won.

Nigbati okunrin na wa iyawo re ti ko si ri on ati awọn omo rẹ ni gbogbo oran na ba su patapata, ti o si fi pinnu pe, "Ọmo mi ku, oya ju omo mi nu lo" ti o si gbe oọẹ le ara rẹ ni abẹdu.

Oku okunrin na wa ni Ile-iwosan lakulaku Ikẹja bayi awọn ọlọpa si nwadi oro na lowo.

## "Ọga Awọn Ọlọpa Ko Faramọ Ẹgbẹ Dẹmọ"

# IJỌBA GE OWO OṢU ỌBA AKARIGBO KU SI KỌBỌ KAN !

SHAGAMU:- Ni deede agogo meji ọsan ana ọjọ Ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi ni irohin kan wa lati ọdọ Aṣoju Iwe Irohin wa ni Shagamu pe, Ijọba Ibilẹ Ijẹbu Rẹmọ ti da Owo Oṣu ti Aṣiwaju awọn Ọba ninu Ilu Igbimọ Ipinlẹ Iwọ Orun awọn Ọba Alaiyeluwa Moses Ṣowẹmimọ Awolesi. Akarigbo Ọba Ijẹbu Rẹmọ duro, Ijọba na yio si ma a san kọbọ kan (1d) ni ẹdun fun Ọba na dipo ẹgbẹfa o le pọnun mejilogun (£1,142) ti Ọba na ti ngba tẹlẹ ni ọdun kan.

Irohin na tun ṣe afikun pe, Igbimọ Afunshọ Ijọba Ibilẹ na tun fẹ da owo iṣalejo, ọgọta pọnun (60) ti Ijọba nfun Ọba na duro.

Igbimọ na tun ṣe afikun siwaju pe, gbogbo anfani ti Ọba na njẹ ninu Aafin rẹ ni awọn yio da duro ti ko si ni ni anfani lati jẹ igbadun Ọba na mọ.

Gẹgẹbi alaye ti awọn ọmọ Igbimọ na ṣe, nwọn ni Ọba Akarigbo ko moju-to gbogbo "rogbodiyan ati



Ọba Awolesi
Akarigbo Ijẹbu Rẹmọ

iwa ẹhanna" ti awọn enia kan nhu larin ilu.

Siwaju si i, Ijọba si tun fi ẹsun kan Ọba na pe, "Ninu Aafin re ni awọn Ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ ti nṣe ipade'

Nwọn tun sọ pe, "o jẹ ohun iyalẹnu lati ri wipe Ọga Agba awọn Ọlọpa ni Shagamu pe, o jẹ ọkan ninu awọn ti nṣe alatilẹhin fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ larin ilu Shagamu, nipa ṣiṣe bayi, o ngbe awọn Ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre pọn ṣẹhin, o si nle awọn Ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ fun ẹkun pajẹ."

Bakanna ni awọn Alaṣẹ Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ṣhagamu tun fi ẹsun kan Ọga Agba fun awọn Ọlọpa Ṣhagamu pe, "O npe awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ sinu ile iṣẹ rẹ, lati maa polowo ibo fun awọn ọmọ ẹgbẹ na'

„AWỌN ỌDẸ"

Lẹhin eyi, ni Ijọba Ibilẹ na tun wa sọ wipe „Awọn ọdẹ ti nwọn nṣọ Ode ni aiẹ larin igboro ilu Ṣhagamu na tun npẹlu ọba Awọn Ode na tun nṣe alatilẹhin fun awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu iṣẹ ti nwọn nṣe"

Ninu ẹsun ti nwọn fi kan awọn ọdẹ ti nṣọ igboro ilu Shagamu, nwọn ni awọn ọdẹ na nṣe iranlọwọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ ti awọn enia na sọ pe, "nwọn nhuwa ẹhanna larin ilu."

Lẹhinti awọn ọmọ Ile Igbimọ na pari ipade wọn nwọn fi ẹnu ṣọkan jẹ, ki akọwe Igbimọ Afunsọ Ijọba Shagamu kọwe si Ile iṣẹ Minista Alamojuto eto Ijọba Ibilẹ Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria, lati ṣe alaiye gbogbo awọn ẹsun wọnyi.

Lẹsẹkẹsẹ ni akọwe Ijọba Igbimọ Afunnshọ na ti kọwe si Oloye Fani-Kayọde Minista, Alamojuto eto Ijọba Ibilẹ ati Igbakeji Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ninu iwe na, Igbimọ na fẹ ki Ile iṣẹ Minista na ko fi aṣẹ si i pe, ki Ijọba maṣe tun gbogbo awọn nkan ti o ba baje ninu Aafin na ṣe mọ Ki Ijọba si fi gbogbo rẹ silẹ

Ijọba na tun sọ ninu iwe ẹsun wọn pe, "Ọba Alaiyeluwa na ki i lu ilu ataiyebaiye ti o wa ninu Aafin rẹ kakiri ilu, bi awọn ti o ti jẹ ọba siwaju rẹ ti ṣe ọba ilu na".



Samuel Akinsanya
Odọgọ Ọba Isara



Oloye F. R. A. Willims

Nigbati oniwe irohin wa Ejongboro ba Ọba na sọrọ ninu Ẹrọgbohungbohun ni irọlẹ ana, Ọba na ṣe alaye pe, on ṣẹṣẹ ri iwe ti awọn enia na fi ẹsun kan on gba ni.

O si sọ wipe, "ko si o'hun ti mo le sọ fun ọ, Ejongboro, nisisiyi, nitori-

Wo Oju Ewe Kẹfa

# ITAN IGBESIAIYE ALAKOSO IJOBA GEESI OLOLA DOUGLAS HOME

Ọlọla Alec Douglas Home si di akọwe agba fun e t o akọwe ọrọ ilẹ okere ni oşu keji ọdun 1960 on lo si rọpo ọgbẹni Selwyn Lloyed ninu iyipada ti Ijọba şe larin oşu na. Ọlọla Alec si t i wa ninu awọn alakoso Ijọba ilẹ Gẹẹsi fun ọdun mẹrun o si ti wa gẹgẹbi akọwe agba fun akoso eto agbaiye lati oşu kẹrin ọdun 1955 lati oşu kẹrin ọdun 1957 ni o ti wa gẹgẹbi o l o r i Ile igbimọ asofin ti awọn agba (House of Lords) ati fun ọdun meji l o s i ti fi wa gẹgẹbi Baba isalẹ ile Igbimọ ti awọn agba.

Ki Ọlọla Alec Douglas Home to lọ si ile işẹ e t o akoso fun Igbimọ agbaiye ni ọlọla 'Alec ti fi igba kan wa ninu awọn Minista alakoşo ninu Ijọba eyi ti ọlọla Winston Churdhill t i jẹ alakoso rẹ, ọlọla Alec si wa gẹgẹbi Minista eto akoşo ilu ti (Scottish).

Gbogbo awọn enia lo mọ ọlọla Home ni ile Igbimọ Aşofin ti nwọn n p e ni (House of Common) fun ọpọlọpọ ọdun ti nwọn npe ni Lord Douglas bi o ti rọpo baba rẹ ninu ọdun 1951 ti o si jẹ enia kẹrinla ti yio gba ipo na lati ọdun 1904 ti nwọn ti da ipo na silẹ. Gẹgẹbi işẹ ti awọn ẹbi o ti wa ninu itan ilu Gẹẹsi lati igba ti Ọba "King Williams the "Lion" ti wa lati ọdun 1914, ọkan ninu enia ti orọpo ọlọla Home ni aşoju ilẹ Scottish ni ilu Gẹẹsi ni 15th Century eyiti nwọn şe atẹle rẹ ni Flodden.

A bi ọlọla Earl Alec Douglas Home ni ọjọ keji oşu keje ọdun 1903, o lọ si ile ẹkọ ni Eton a t i Christ Church ni ilu Oxford ibẹ na lo ti gba oye giga ninu I t a n. Nigbati o k u r o ni Oxford o si fẹran lati şe oşelu Nigba na lo di olori Scottish Unionis. Association, Nwọn mu silẹ gẹgẹbi aşoju fun ẹgbẹ Conservative fun ilu Coarbridge ko si wọle ile lasiko na ninu ọdun 1929, Şugbọn ni ọdun 1931 o si wọle ile Igbimọ aşofin fun ilu Lanark ibi kan pataki to jẹ ilu ti nwọn ti da ile işẹ orişirişi s i l ẹ to si jẹ pe awọn enia to nwa awọn ohun işura ni lo si ibẹ ee wọle idigbo igba na. Ọlọla Alec si wa ninu ile Igbimọ Asofin na lati ọdun 1945 si 1950 titi o fi lọ si i l e Igbimọ aşofin awọn agba t i a n p e ni (House of Lords)

Ọlọla Douglas si wa gẹgẹbi akọwe agiri ni ile Igbimọ aşofin fun akọwe alakoso ijọba fun eto ilu ni Scotland ọgbẹni Skelton fun odidi ọdun mẹrin to fi wa ni ile Igbimọ asofin ti (House of Common) lẹhin t o tun şişẹ fun awọn Minista Alakoşo kekere meji awọn si yan ọlọla Alec ni ọdun 1936 gẹgẹbi akọwe ile Igbimọ aşofin fun ọgbẹni Neville Chamberlain lẹhin na ni o di olori ile ẹkọ giga t i Exchequer ọlọla Alec si wa ni ipo na titi ọgbẹni Chamberlian fi işẹ eto ọrọ oşelu silẹ ko si pẹ ti o si ku.

Lẹhin ti ọgbẹni Chamberlain fi işẹ o r ọ oşelu silẹ tan ni ọlọla Douglas Home tun wa gẹgẹbi ọga kan ni Lenarkshire Yeomanry fun ọpọlọpọ ọdun to si tun pada wa di ọmọ ogun. Ọlọla Douglas şe aisan t o fi di pe nwọn sọ fun pe ki o fi işẹ ọmọ ogun silẹ ati pe ki o ma şe, şe işẹ eto ọ r ọ oşelu fun odindi ọdun meji tabi mẹta ninu ọdun 1943 o si pada si işẹ oşelu ti o si fi igba na fi gbogbo ọjọ aiye rẹ şe oşelu ti o si fi ma ngbọ eto ọ r ọ oşelu lati ilu okere ti o wa di ogbokangi sinu eto ọ r ọ oşelu. Ọlọla Douglas Home gba ipo Minista ninu eto ijọba alamojuto ninu ọdun 1945 ti o si wa g ẹ g ẹ b i alakoso eto okere.

Ọlọla Douglas si kuna ninu eto idibo ni ọdun 1945 şugbọn o si bori ibo n a pada ninu ọdun 1950.

Lẹhin to ti rọpo baba rẹ ninu oşu keje odun 1951 o si gba ijoko ni ile igbimọ aşofin (House of Lords) osi sibẹ gẹgẹbi Lord Douglas gẹgẹbi eto ipo ti ilu Gẹẹsi ti nwọn fun ẹni kọkan ti yio gba ipo oye na ti o si jẹ ti idile ti ọlọla Douglas Home ni Ọdun 1875.

Nigbati awọn ọmọ ẹgbẹoşelu ti anpe ni Conservative Party tun goa ijọba ninu ọdun 1951 nwọn tun yan Lord Home si ipo minista eto ilu ati pe on si ni ẹni akọkọ ti yio kọ wa nlau ipo na. Gẹgẹbi o se lo ipo na si nwọn tun yan gẹgẹbi ọkan ninu awọn ti yio ma gbọ ẹjọ kotẹmilọruu ti ile ẹjọ giga julọ ni ilu Gẹẹsi ọlọla Alec si pọ to bẹ to fi tun je pe on kan na lo wa gẹgẹbi igbakeji alakoso eto ilu Scotland fun gbogba ayika ile Scottish o si fi ara rẹ mọ eto awọn ile işẹ fun idagbasoke ati ile işe ti nwọ ti nse nkan orişirişi ati fun gbogbo awọn oke ati ereku su na lo si nbojuto papa fun eto ijẹba ibiie ọlọla Alec si tun mọ nipa eto akoso ọrọ ẹkọ

Gẹgẹbi asiko ti ọlọla Douglas jẹ alakoso eto agbaiye ti o si yi pada nipa iyipada to si Wa ninu eto na tun nwu ki işẹ rẹ tun pọ ju gẹgẹbi oti wa tẹlẹ to si je pe o mu eto akoso ti ilẹ Malaya ati Ghana ọlọla Home si şe abẹwo awọn ilu to pẹlu ajo ile agbaiye lasiko to wa lori ipo na.

Ọlọla Home si tun rin kakiri gẹgẹbi alakoso eto ilu okere eto irin rẹ najẹmọ eto bi awọn ilu okere yio şe gbọ ohun ara wọn lori eto ọgbọn ati ilopọ pẹlu ilu Gẹesi nipa ọrọ eto okere bi ile tabi ti nwọn ba jijọ pade lode

Ọlọla Alec si tun şe eto nipa ibẹwo si apa iwọ orun agbaiye ni awọn ilu to gba ominira ati fun işẹ ti awọn ilu na nşe ati papa fun eto awọn ilu ti ko ti ni ilọsiwa ju ni orilẹ agbaye ati pe eto rẹ si tun jẹ mọ ti igbimọ agbaye ati fun ẹdun ọkanrẹ lati ri awọn igbimọ gẹgẹbi fun lilo fun eto alafia ati lati mọ iru alafia wo la ni

Ọlọla Alec Douglas gbe ọmọ Alufa Dokita C.A Alington ẹniti o ti jẹ ọga ile ẹkọ ni Eton ni iyawo ninu

WO OJU EWE KARUN



ỌLỌLA ALEC DOUGLAS HOME

# Awọn Ọmọ Ẹgbẹ N C N C ati A G Kọ Iwe Si Azikiwe

ILESHA:— Ni Ọjọ Ọjọ'Ru ti işe Ọjọ kẹtadinlogun Oşu yi ni awọn Ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre ni agbegbe Ijẹsha kọ iwe ikilọ si Arẹ ilẹ Naijiria Ọlọla Dọkita Nnamdi Azikiwe ati olotu ijọba apapa ilẹ Naijiria Ọlọla Alhaji Abubakar ni pa iwa ti awọn Ọmọ ẹgbẹ Oselu kan nhu si awọn Ọmọ ẹgbẹ wọn nipa fifi iya jẹ wọn ati ki awọn ẹgbẹ Oşelu na ma a ba ile ati awọn ikan ini wọn jẹ.

Iwe ikilọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ na şe ti nwọn si tẹ ni waya si Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Oloye Fadahunsi, Olotu Ipinlẹ Ila Orun Dọkita Okpara, Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun Oloye S. L Akintọla. Alhaji D. S. Adegbenro Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Ọga agba awọn Ọlọpa.

Awọn ẹgbẹ meji na sọ ninu ọrọ wọn pe awọn Olori ẹgbẹ Dẹmọ (N N D P) to wa ni agbegbe Ijẹsha si lọ ra apoti ada mẹrin at awọn ohun ọşẹ miran si agbegbe Ijẹsha ni asiko ti Olotu Ipinlẹ Ila Orun Dọkita Okpara şe ibẹwo si Ipinlẹ Iwọ Orun laipẹ ti o si rin irin ajo rẹ de agbegbe Ijẹsha.

Awọn ẹgbẹ na si tun sọ pe awọn Olori ẹgbẹ Dẹmọ tun sọ fun awọn Ọlọpa Ibi lẹ to wa ni agbegbe na pe ki nwọn ma şe gba iduro fun awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ Afẹnifẹre ti nwọn ba ti mu.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun bu ẹnu ẹtẹ lu awọn Ọba.

Iwọ Orun nipa ikuna wọn gẹgẹbi baba fun awọn enia ipinlẹ na lati le dẹkun si rogbodiyan to nbẹ silẹ ni Ipinlẹ na larin ẹgbẹ awọn ọmọ oşelu.

Ni ọjọ ọjọ'Ru ti işe ọjọ kẹtadinlogun oşu yi ni ijọba ibilẹ Ibadan kesi awọn Ọlọpa lati le ba wọn dẹkun eto ofin to bẹ silẹ ati lati le ba wọn şe gẹgẹbi nwọn yio şe da ẹmi awọn enia si ni arin ilu.

Ijọba ibilẹ na tun sọ pe, ti ko ba si ti awọn ẹgbẹ Oşelu kankan eto wọn ni lati le je ki alafia ati ifọkan balẹ wa larin ilu.

# Yẹ Irawọ Rẹ wo

AGUARIUS (Jan 22-Feb 20) O yẹ ki o şe ipionu kan lọsẹ yi jẹki ara rẹ mọ gedegbe laiba ẹnikan pade Bi oşe wipe ọrọ rẹ da ọ loju nwọn le pari ija kan ti o wa nilẹ.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Bi o ba le gbagbe wahala ojojumọ, iwọ yio lo akoko alagbayun pelu ọre re obinrin ọgbọn ori re ni yio şe atọna rẹ, şọ awọn ọrẹ ti iwọ yio gbọkanle,

ARIES (Mar 21-April 20) Şọra rẹ nitori jamba ti yio şẹlẹ ni ojude rẹ bo simi loni ki o sun orun arẹ diẹ, ohun kan to şẹşẹ jade yio jẹ tirẹ bi o ba lọrẹ ododo.

TAURUS (April 21-May 20) Maşe gbidanwo lati tẹ ara rẹ lọrun laiti ri ododo ọrọ dimu. Maşe şe ere ipa ti yio mu ọ di alaisan, maşe fi aşiri rẹ han ẹnikan, ki gbogbo ohun ti o ngbero lọkan le dara.

GEMINI (May 21-June 21) Şọra loni, ki jamba kan maşe şẹlẹ si ọ ki gbogbo ara ma ba dun ọ. Ewu ambẹ ninu wipe ki o ti ibişẹ kan bọ si ekeji, maşe yi ọjọ pade ki o ma jasi opin rẹ.

CANCER (June 22-July 23) Şọra, fi aju rẹ silẹ, ma şe fi oju fo enia da, ki o si şe suru, ipọnju ile le mu ọ fi oju fo işẹ atata kan, maşe foya iranlọwọ mbọ lati ọdọ Ọlọrun.

LEO (July. 24-Aug. 22) Maşe wọ işẹ tuntun kan ni akoko yi. Şọra ki o maşe fi ara ko arun-alarun. Şọra nitori ọrọ ti iwọ yio sọ ti iwọ yio tun maka abamọ nipa rẹ.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Akoko rere kan lo nlọ yi, ohun ti o dara fun ọ ni ki o dimu, şe pẹlẹpẹlẹ ni alẹ yi, ki o ma ba ko arun ni alẹ yi.

LIBRA (Sept 24-Oct23) Maşe lọ sibi kan ni ọjọ Satide ti o mbọ yi şe işẹ rẹ tọkantọkan ki ọsan oni ba le miringindin fun ọ fi ọkan rẹ si işẹ rẹ, ki o masi şe lọ si ode oru.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Orişirişi nkan ni yio şẹlẹ lowurọ yi, maşe jade lọ sibi kan ọjọrọ yio gbadun fun ọ. Maşe gba fun awọn to ngbero lati da ọ lamu,

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Maşe lọ si idalẹ kan lọjọ oni, aya fi ti o ba ni garangda, şọra nipa awọn nkan olori buruku ti nwọn fi nşe adauwo fun ọ

CAPRICORN [Dec 22-Jan 21) Nwọn le gbe işẹ Samuel kan le ẹ lọwọ pe ki o şee, alalikua iwọsi ni wọ yio gba nibẹ maşe fi işẹ kan silẹ laişe ki o din aaji rẹ ku maşe lọ si ibikan inu ile işẹ rẹ ni ki o wa.


## Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin yọ De

Ojulowo Egbogi awon Faranse gidi ti a npe ni

**'CORSIVER'S**



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a şe ni pataki Fun „ARỌN KINIŞA" tabi LATANLATAN ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹrau tabi lati ma şe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba ti lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹnu sibẹsibẹ bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo şe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn amodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi ra ojẹ ni şọbu awọn

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos
Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos

BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Işẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

KỌWE SI ILE—IŞẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**
16. Bamgboşe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lago s.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanşoşo ko si ri iyatọ*

# Ogundele Saigboran

Lati owo R. A. DUNMOYE Okeya, Igbomina.

Omode peku o muje omode j » ova o muje, ojo ti omo de ba pa oro nko? ki nto bere itan mi, ngo koko dupe lowo Olotu Irohin Imole fun tite ti o nba mi te awon itan mi jade lasiko ko ni si te oko oba ko si ni ṣa a lese. Bakan na ni enyin ti o nka itan mi, ko ni re yin aitoju ko si ni ba nyin ogbon ati oye temi na ko ni daru mosi tun dupe lowo iyawo mi ti oran mi lowo (Emi ko ni daru ko re ki o ma ba di ejo) Ati olotu, ati onkawe ati emi opitan oro ejo ko ni ba wa o (Amin)

Ẹnyin ti e ba nka itan mi, e o ri wipe "bi owe bi owe ni a nlu agidigbo, ologbon nijo omoran ni si n.o toto se bi owe o

Itan mi ti ose yi dori ko dori, o dori baba olode kan ti o bi omo kunrin meji oru ko ekini nje Adeniyi oruko ekeji si tun nje Osundele Nigbati awon omo mejiji yi dagba toju bo baba nwon bere lowo awon iru ese wo ni elukaluku nwon fe lati se.

Adeniyi fesi wipe ise ode sise ti awon ba lowo baba awon ni on yio se. Oguudele dahun wipe agbe ni on fe se.

Gegebi eti mo, enia bu ruku gba a ni Ogundele ise oju kokoro Ogundele ju ti ekute ile lo, okanjuwa re si poju ti aja ti ogbe egungun lo. Ogunde ni okanjuwa de bi wipe ti nwon ba nfi nkan ran nise si Adeniyi egbon re, Ogundele ko ni fi jise.

Bi Adeniyi ba pa eran loko ode yio gba wa sile gbogbo nwon ni yio jijo fi se ata, sugbon Ogundele ki mu isu tabi agbado wa sile bi o pa ekute, a da nkan re je, bi nkan ogbin re ba si po, a ko nwon ta a si da owo re na.

Baba re pe o kilo fun ki o ye da nkan re je, o so fun Ogundele titi, Ogundele ko gbo ko si gba.

OGUNDELE ṢAIGBO-RAN

Nigbakigba ti baba ba ti pari oro re a pa owe yi fun wipe ' Omode pekute, o da je, omode poya o da je, ni ojo ti omode ba pa oro nko?"

Laibikita Ogundele ko ehin eti si gbogbo imoran baba re, o si nyo ninu ibaje, Ẹgbon re Adeniyi ti o ti di ogbolobo ninu ode na tile ti kilo fun un sugbon erin ni Ogundele nrin lwo enu Ogundele si ju ti eniti o ni on mo ojo ti nwon gbe iya on ni iyawo.

"ẸṢAN KI LORI ALAIGBORAN

Ni igbati o di ojo kan Ogundele lo si oko, gbara ti o de oko lowuro kutukutu, o pa ejo paramole kan. O pada lo si ile, o de ile, gegebi iwa re, alaigboran ko so fun enikankan o se ejo si inu ipasun re.

Nigbati o see jina tan o bosi inu yara re o si ti ilekun mori, ki elomiran ma ba be je ninu re,

Bi Ogundele ti joko lati ma ba faji I ni ejo paramole yi ba tu ninu nranran inu ipasun, O so fun Ogundele, a ni yo oke ki o wo ile oni ti ojo iku re pe Ogundele fa igbe ta o k e lohun rara oni "Adeniyi ode o; jowo gba mi s i l e lowo ejo yi o." Oro omo iya kan pa pa, Adeniji de o si pa ejo na. Ni ojo na si ni Ogundele to wa mo itumo owe ti baba re ma npa fun un. Adeniji si gba Ogundele sile lowo iku ejo oloro.

Ẹnyin ara, eko pataki ti o wa ninu itan yi ni wipe, aigboran, iya ni fi je ni Ẹnyin omode e gboran si awon obi nyin lenu, e ma si se jeki o pe ki o to ye nyin bi ti Ogundele-Igboran sanju Aigboran lo.

Emi Omo DUNMOYE, Apatan bi eni wa nibe, mo nrele o Bi mo ba ti nri iwe nyin pe e gbadun itan mi beni e o ma gbo orisirisi, nitoripe bi egungun eni ba jore o i aya ni,

O digba.

## Itan Igbesiaiye Alakoso Ijoba Geesi

Lati Oju Ewe Keji

odun 1936 on pelu iyawo si bimo okunrin kan ati omo obirin mefa iya afin Home si ti ba oko re rin opolopo irin ajo to rin.

Olola Lord Home je olu dajo ibukun ni ilu Lanarkshire ati igbakeji oga awon omo ogun ti Ilu Berwikshire olola Alec feran ere bolu ti nwon fi igi ngba o ti se asoju fun Middlesex ninu ere idije bolu onifi igi gba olola Alec tun gba oye omo ogun ninu Osu kewa Odun 1962.

WON EGBOGI ATAMATASE PATAKI TIO WA LATI ILU JAMANI FUN ITOJU ARUN ARA ATI OJU-DIDUN PELU EKINI:-

SEDO — PAYAL



(IPARA BI ORI)

Je ojulowo egbogi lati fi se iosan orisirisi arun awon ARA" gbogbo ti o ba mba enia ja lara tabi o de ara egebi owo ese tabi ara hihun tabi didun nigbakugba naron tabi ako Inarun, Ewo, Rore kakiri oju, Ela lapa a pa Ara sisu Alefo Ekuse lori omode tabi agbalagba egbo ese tabi Adaajina egbo ese ati orisirisi awon amodi tabi awon arun ara om ran gbogbo.

BẸNA SI EGBOGI

Dara pupo julo fun awon ti amodi ti a daruko won si oke iwe yi ba nyo lenu nitoripe ise re ni lati ma mu gbogbo awon "kokoro" buruku gbogbo ti o ba wa ninu "IJE ARA" enia, san patapata a si ma a ise ribiribi ninu "oju" enia pelu. Awon ti oju won a ma "nsu" tabi wo baibai tabi ti won ko le riran daradara lati ona jinijini tabi ti o bdai enipe nkankan wa afara si oju won yio bere si riran Kedere.

Bi o ba ti le gbiyanju lati ma lo egbogi Jamani yi dede fun igba die alafia yio de si o ju gbogbo re lo egbogi Furunculosin yi a tun ma mu igbouse woro woro wa fun awon ti inu won bale tabi ti won ki rigbonse dede lojojumo tabi ti igbonse won ma nle koroкoro nipa bayi jedijedi a bere si ma yo won lenu beni o si dara fun lilo fun awon onijedijedi pelu awon egbogi meji yi yato si gbogbo awon robirobi ti won nta kakiri Ṣobu ilu Eko ati igberiko Bere won ni Ṣobu awon:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS
Because Of Their,—

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 — Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

Modupe Printing Press

16, Bamgbose Street
Phone21985, Lagos.

# IROHIN IMỌLE

IMỌLE ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No, 279 FRIDAY JUNE 26, 1964 (2D)


## Ọwọ Awọn Ọlọpa Tẹ Onijibiti Kan

YABA:- Kẹkẹ pamọ gbogbo enia lenu nigbati awọn Ọlọpa mu ọdaran kan, Mufuntau Onigbanjo, wa siwaju adajọ Agba Ile ẹjọ kekere Yaba ni ọjọ OjọRu ti iṣe kẹrindinlogun oṣu yi fun ẹsun ole jija ati jibiti.

Ẹsun ti awọn ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣẹjọ fi kan an niwaju adajọ ni pe, ọdaran na lọ si Banki kan ni Yaba, o si ji adọta-le-lẹgbẹrun p,nun (£1, 050) gbe ninu Banki na. Ọlọpa na tun ṣe alaye siwaju pe lọwọ akọwe l e owo na ni ọdaran na ti gbe owo na ni pe, on yio ba ṣe ilopomeji rẹ ti o fi jẹ pe owo na yio di ẹgbẹdẹta o din ọgọrun ponun. (£2, 500),

Ṣugbọn nigbati awọn enia ti o wa nibẹ sare wa ṣe awọn Ọlọpa leekanna ni awọn Ọlọpa si ragabu Ọdaran na lẹsẹkẹsẹ ni Ọdaran na sọ pe, "Ọlọpa ṣebi nitori owo ni o ṣe nṣiṣẹ, gba Ọgọrun ponun (£100) yi sọwọ na, " o si fun Ọlọpa.

Ọlọpa na tun ṣe alaye pe, adota le ni iriwo ponun (£450, lọ sọ pe on yio fun awọn Ọlọpa ti nwọn ba le fi on silẹ, ṣugbọn Ọgọrun p,nun (100) pere lọ fun wọn Awọn Ọlọpa ko gba owo na nwọn si mu u lọ si Tesan awọn Ọlọpa,

Adajọ ko tile gbọ Ọrọ lenu Ọdaran na, ti o fi yẹ gbigbọ ẹjọ na si Ọjọ iwaju Ṣugbọn bi nwọn ba ti pari ẹjọ na si, ẹ o ma a gbọ ninu iwe irohin wa.

## Ina Nla Kan Jo Ni Igboro Ilu Kano !

# ERU ẸGBẸRUN PỌNUN (£1,000) ṢEGBE SINU ILE !!

KANO:— Gbogbo ilu lo gbojikan fun ariwo ti idaamu nla si ba gbogbo awọn ara ilu nigbati ina nla kan bẹrẹsi jo ni inu ile Ero kan, ni nọmba 12, City Road, Kano fun odidi wakati meji ti gbogbo awọn ohun elo inu ile na eyiti iṣiro rẹ jẹ ẹgbẹrun ponun (£1,000) jona tan rau-rau ni alẹ ijẹta ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi.

Iyaafia Paulina Ashiloni, ẹniti o ni ile Ero (Hotel) n ṣe alaye fun oniwe irohin wa ni Kano pe on ko mọ bi ina na ti ṣe ṣẹlẹ, ṣugbọn siwaju eyi ni on ri eefin kan ti o ntu jade lati inu yara labẹ timutimu ori ibusun on.

O tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, boya ọkan ninu awọn ti nwọn wa nra ọja lọdọ on ni nwọn mu siga ti nwọn si gbagbe ina siga wọn si ori timutimu ori ibusun na.

Nigbati on joko si ode ile na, ṣugbọn nigbati on yio fi fura si i ina na ti bẹrẹsi ijo, gbogbo ile na si jo kanlẹ patapata.

Bi ina nla na ti ṣẹlẹ ni awọn Ọlọpa ati panapana ti sare de ti nwọn si wa pa ina na, ṣugbọn ile n a jo kanlẹ bamubamu ti gbo gbo awọn ẹru inu ile na si jona di eeru !

Bi ko ba si awọn Ọlọpa ati panapana ti nwọn tete sare de, ina na ki ba jo to ile marun ti nwọn fi ẹgbẹ kan ara wọn ni opop ati adugbo na.

Nigbati ile na jona tau, Paulima Ashilonu ti o ni ilẹ na ṣe iṣiro iye a w ọ n ohun elo ti o wa ninu i l e na ti iye owo wọn si j ẹ, ẹgbẹrun ponun (£1,000)

Awọn Ọlọpa t i bẹrẹsi iṣe iwadi ohunti o o fa ina ti o jo ile na.

Ọkọn ninu awọn Ọga Ọlọpa ti wa nitẹ ṣe alaye fun oniwe irohin pe, boya ọkan ninu awọn ọkunrin ti nwọn jẹ ọrẹ Obinrin na lo ta ijamba na fun un ṣug'ọn bi awọn Ọlọpa ba ti wadi ọrọ na si, ẹo maa gbọ.


## Ẹgbẹ Ọmọ Ibilẹ Takete

Afi Iwe yi pe gbogbo awọn Ọmọ Ibilẹ Takete— ati gbogbo Agbegbe rẹ lọkunrin ati lobinrin ti wọn ngbe ni Ilu Eko ati Agbegbe rẹ si ibi ipade pataki ti ao se ni ọjọ kejidinlogbọn (28:6:64) oṣu ti awa ninu re yi ni No. 1, Coates Street Ebute Metta ni agogo meji ọsan. Pataki ọrọ ti ao sọ ni pa re ni ilọsiwaju gbogbo ọmọ Ibile Takete ti o wa ni ilu Eko.

LATIFU ADEJẸBI
AG Chairman


## Ijọba Ge Owo Oṣu Ọba Akarigbo Ku Si Kọbọ kan


LATI OJU EWE KINI


pe, nko fẹ ṣe gbolohun ọrọ lori ọrọ na",

O tun sọ siwaju pe "Nko ni sọ ohunkohun lori Ọrọ na, titi ngo fi mọ ohun ti Ijọba Ipinlẹ yio ṣe lori Ọrọ na,"

Oniwe irohin wa tun ba awọn Alaṣẹ Ile iṣẹ Minista Alamojuto eto Ijọba Ibilẹ sọrọ lori ẹrọ gbohungbohun ni Ọsan ana ṣugbọn ẹniti o dahun lori ẹrọ na kọ lati sọrọ lori Ọran na, o kan ki Ejongboro pe, "Ẹ ku atijọ o ṣe Eko dun o "Ṣugbọn Oniwe irohin wa dahun pe "Ọrọ Eko ko ni mo fẹ ba ọ sọ."

Onirohin wa kan ran wa leti pe lenulọloyi ni Ijọba yọ Ọba Samuel Akinsanya Alaiyeluwa Ọdẹmọ Ọba Ishara, ati Oloye F. R. A Williams kuro ninu Ile Igbimọ awọn Ọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Bakanna ẹwẹ, onirohin wa tun sọ ṣiwaju, ni Ijọba tun ṣe ipinnu pe, kọbọ kan (1d) ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria yio maa san fun ọba kan ni agbegbe Ekiti.

Onirohin wa na tun sọ pe, ko ti si ifaiya bẹle ni Ipinlẹ Iwọ Orun lati bi Ọdun meji sẹhin.

Ni deede agogo mẹfa irọlẹ ana ni awọn Ọlọpa bi ọgọta tun lọ si Ibadan lati dẹkun ija ojojumọ ti o nṣelẹ ninu ilu na.

O tun gbọ pe, ija ti wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ kan ni igboro ilu Shagamu, nitori ọrọ na ni Ijọba ṣe sọ pe, awọn ko ni san owo oṣu (£1, 142) fun Ọba Akarigbo mọ, awon yio si ma a san kọbọ kanṣoṣo pere (1d) fun Ọba na ni ọdun kan.

Bi Ijọba ba si ti pari ọrọ na si ẹo tuu m a a gbọ ninu iwe irohin wa.


Printed aud Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbohe Street Lagos Phone 21985
Editor:- TUNJI ADEỌSUN 46, Campbell Street Lagos 26/6/64